**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**
Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.
**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**DÍDÒJÚKỌ ÀWỌN Ẹ̀MÍ ÒKÙNKÙN**
**ÀJÀKÁLẸ̀-ÀRÙN TÓKÁRÍ AYÉ (6)**
**OṢÙ KẸ́JỌ 2022**
Ìwé Mímọ́ kíkà: Orin Dáfídì 17; 27; 91
Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ọ̀tá tó n ṣètò láti wá sínú ayé mi láti pamírun, Ọlọ́run dìde, jẹ wọ́n run, ní orúkọ Jésù.
6. Àjọ àjẹ́ ìyówù, tó n ṣiṣẹ́ lórí orúkọ mi, gba ìjákulẹ̀ nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa, fún mi ní ore-ọ̀fẹ́ àti ifòróróyàn láti borí, ní orúkọ Jésù.
8. Gbogbo ọwọ́ àjèjì, tó n dá àwọn ìyanu tí Ọlọ́run ti ṣètò fún mi dúró, gbẹ dànù nípa iná, ní orúkọ Jésù.
9. Olúwa, sọ ìyanu mi di ìlọpo-ìlọpo lóṣù yìí, ní orúkọ Jésù.
10. Olúwa, jẹ́ kí àwọn ìyanu tí n kò retí, tí yóò jẹ́ kí n rẹ́rìn ṣàwárí èmi àti ìdílé mi, ní orúkọ Jésù.
11. Oṣù yìí kì yóò mú ibi wá sórí èmi àti ìdílé mi, ní orúkọ Jésù.
12. Gbogbo àjàgà àídọ́gba tí mo ti wọnú rẹ̀ lọ, Olúwa, mú mi kúrò nínú rẹ̀ lónì, ní orúkọ Jésù.
13. Májẹ̀mú ibi aìmọ̀, tímo wọ̀ lọ pẹ̀lú ẹ̀jẹ̀ mi, gbiná, ní orúkọ Jésù.
14. Gbogbo agbára tó n gbin àwọn àmì ibi sínú ayé mi láti pamí, gba itìjú, ní orúkọ Jésù.
15. Gbogbo àdàlù ìrandíran tóti dàpọ̀ mọ́ ẹ̀jẹ̀ mi, ẹ̀jẹ̀ Jésù, fọ̀ ọ́ dànù lónìí, ní orúkọ Jésù.
16. Gbogbo ètò ibi láti fa ẹ̀jẹ̀ mi mu àti láti jẹ ẹran-ara mi, ta padà, ní orúkọ Jésù.
17. Olúwa, sọ ẹ̀jẹ̀ àti ẹran-ara mi di kòṣè è fọwọ́kàn, ní orúkọ Jésù.

**18.**Àwọn agbára tó dá ọkọ̀ ayànmọ́ mi gúnlẹ̀ sábẹ́ ìdíyelé, ẹ túká, ní orúkọ Jésù.
**19.**Àwọn agbára tó n kó abọ̀dè bá orúkọ mi fún ibi, gba itìjú, ní orúkọ Jésù.
**20.**Mo yọ ẹ̀jẹ̀ mi kúrò nínú gbogbo ìfinijì ibi, ní orúkọ Jésù.
**21.**Olúwa, pàṣẹ fún gbogbo ogun tó gbé mi mìn, kó ó pọ̀ mí sílẹ̀, ní orúkọ Jésù.
**22.**Olúwa, fún mi ní ẹni inú tuntun, tí a bá ti kó àdàlù bá mi, ní orúkọ Jésù.
**23.**Agbára àjèjì ìyówù, tó n ta ẹ̀jẹ̀ sílẹ̀ nítorí mi, kí àṣírí rẹ tú, kosì gba itìjú, ní orúkọ Jésù.
**24.**Ìwọ ayé mi, fi àwọn ohun tuntun hàn, ní orúkọ Jésù.
**25.**Àfonífojì nlá lárin èmi àti àwọn olùrànlọ́wọ́ mi, dípa, ní orúkọ Jésù.
**26.**Olúwa, mú mi jáde kúrò nínú gbogbo àfonífojì tó n dí ògo mi lọ́wọ́, ní orúkọ Jésù.
**27.**Ogun tíkò jẹ́ kí wọ́n kí mi kú oríire, Olúwa, paárun, ní orúkọ Jésù.
**28.**Agbára òkùnkùn ìyówù tó n lo òjìjí láti bámi jà, Olúwa, gbé wọn dè, ní orúkọ Jésù.
**29.**Gbogbo olùta ayànmọ́, tó n ta ògo àti ayànmọ́ mi nínú àwọn àjọ wọn, ẹ̀ gba ìmúso, ní orúkọ Jésù.
**30.**Ìdà tí àwọn ọ̀tá mi fi ìgbẹ́kẹ̀lé wọ́n lè lórí yóò pawọ́n run lójijì, ní orúkọ Jésù.
**31.**Olúwa, jẹ́ kí ikú jẹ àwọn àgbà ìkà tó n fimí ré, ní orúkọ Jésù.
**32.**Gbogbo ọfà àdánù nlá, tí wọ́n rán lòdì sími láti pamí lẹ́kún, padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, ní orúkọ Jésù.
**33.**Gbogbo ọfà tí wọ́n yàn láti jẹ́ kí n ṣe àwọn aṣìṣe tíkò látùnṣe, ta pàdà, ní orúkọ Jésù.
**34.**Idà atòkèwá, ṣàwárí àwọn àjèjì tówà nídi ọ̀rọ̀ mi, kosì pawọ́n run, ní orúkọ Jésù.
**35.**Olúwa, fòróróyàn mí láti gba gbogbo ọdún tímo ti fi ṣòfò dànù ní gbogbo agbègbè ayé mi padà, ní orúkọ Jésù.
**36.**Agbára ibi ilé bàbá mi, tó de ògo mi mọlẹ̀ sójúkan, àkokò rẹ dópin, gbiná, kosì kú, ní orúkọ Jésù.
**37.**Ìwọ ayé mi, mú ohun tuntun jáde, ní orúkọ Jésù.
**38.**Ìrànlọ́wọ́ tíkò ṣe e dádúró, láti agbègbè tímo n retí àti èyi tí n kò retí, ṣàwárí ayé mi, ní orúkọ Jésù.
**39.**Gbogbo agbára tó n fi àwọn àlá àìláṣeyọrí gbógun tìmí, túká sí wẹ́wẹ́ nípá iná, ní orúkọ Jésù.
**40.**Agbárákágbara tó wí pé n kò ní tẹsìwájú, gba ìtìjú, ní orúkọ Jésù.